# JAKỌBU SURE FUN AWỌN ỌMỌ RẸ̀ -- AWỌN ASỌTẸLẸ NLA NIPA MESSIA

**Gẹnẹsisi 48:1-22; 49:1-33**

**ẸKỌ 40 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Emi ri i, ṣugbọn ki iṣe nisisiyi: emi si wò o, ṣugbọn kò sunmọtosi: irawọ kan yio ti inu Jakọbu jade wá, ọpa-alade kan yio si ti inu Israẹli dide" (Numeri 24:17).**

**I Jakọbu sọ awọn ọmọ Josẹfu di ti rẹ̀, o si sure fun wọn**

1 Lẹyin ti Jakọbu tun fi idi majẹmu ti Ọlọrun ba a dá ni Bẹtẹli mulẹ, o sọ awọn ọmọ Josẹfu di ti rẹ̀, Gẹnẹsisi 48:1-7

2 Jakọbu kí Manasse ati Efraimu, o si yọ̀ nitori Ọlọrun jẹ ki o ṣe e ṣe, Gẹnẹsisi 48:8-12

3 Jakọbu, arugbo, ẹni ti oju rẹ ti di baibai, nipa gbigbe ọwọ ọtun rẹ̀ si apa osi, ati ọwọ osi rẹ̀ si apa ọtun, o sure ti o pọju fun eyi aburo, Gẹnẹsisi 48:13-16

4 Josẹfu lodi si iyipada ti baba rẹ̀ ṣe ni kikọ̀ lati sure akọbi fun Manasse, Gẹnẹsisi 48:17-19

5 Jakọbu fi idi ohun ti oun ṣe mulẹ, o si fi aburo ṣaaju ẹgbọn, Gẹnẹsisi 48:19-22

**II Ire Ti A Sú Fun Awọn Ọmọ Mejila Naa Jẹ́ Asọtẹlẹ**

1 Aiṣedeedee ati ẹ̀ṣẹ̀ mu ki Reubẹni sọ ipo giga nù, Gẹnẹsisi 49:1-4; 37:21, 22; 42:22; Deuteronomi 33:6; Awọn Onidajọ 5:15, 16

2 Iwa ikà ati ẹ̀ṣẹ Simeoni ati Lefi mu ki a pín ogún wọn ki a si tú wọn ká, Gẹnẹsisi 49:5-7; 34:25-31; Ẹksodu 32:26-29; Numeri 1:47-54; 26:62; 35:1-8; Deuteronomi 33:8-11

3 Ogun-ibi ti Juda jẹ́ ti ọba, nipasẹ rẹ̀ ni Messia ti jade wá, Gẹnẹsisi 49:8-12; Deuteronomi 33:7

4 Ileri ti a ṣe fun Sebuloni jẹ́ ti oniṣowo nla ti yoo maa ti ebute kan dé ekeji, Gẹnẹsisi 49:13; Deuteronomi 33:18, 19; Awọn Onidajọ 5:14, 18

5 Asọtẹlẹ nipa Issakari n sọ nipa wiwà ni itẹlọrun ninu ainilaari ẹya naa, Gẹnẹsisi 49:14, 15; Deuteronomi 33:18, 19; Awọn Onidajọ 5:15

6 Dani, arakunrin ti ki yoo ri oju rere pupọ gbà, yoo mu ipa ti rẹ̀ ṣe sibẹ̀ laaarin awọn eniyan, Gẹnẹsisi 49:16, 17; Deuteronomi 33:22; Awọn Onidajọ 5:17

7 Gadi yoo ri iṣoro, ṣugbọn yoo bori nikẹyin, Gẹnẹsisi 49:19; Deuteronomi 33:20, 21; Awọn Onidajọ 5:17

8 Ipin ti Aṣeri yoo jẹ́ ti ọlọrọ, ti o kun fun ọ̀ra ati adidùn, Gẹnẹsisi 49:20; Deuteronomi 33:24, 25; Awọn Onidajọ 5:17

9 Naftali ni a fi ipin ọ̀rọ rere ati ọgbọ́n fun, Gẹnẹsisi 49:21; Deuteronomi 33:23; Awọn Onidajọ 5:18

10 Josẹfu gba ibukun ti o pọ ju gbogbo wọn lọ, apapọ gbogbo ibukun ti awọn baba nla; ati ilọpo meji ogun-ibi, Gẹnẹsisi 49:22-26; Deuteronomi 33:13-17; Awọn Onidajọ 5:14

11 Bẹnjamini, abikẹhin ni a fi ibukun agbára ati ọrọ̀ fún, Gẹnẹsisi 49:27; Deuteronomi 33:12; Awọn Onidajọ 5:14

**III Asọtẹlẹ Nipa Messia Ati Iṣẹ́ Ikẹyin Ti A fi Le Wọn Lọwọ**

1 Ọpọlọpọ asọtẹlẹ nipa Messia ni a ri ninu awọn majẹmu naa, Gẹnẹsisi 3:15; 6:18; 12:3; 17:21; 22:18; 28:14; 46:3; 49:10; Numeri 24:17; Deuteronomi 18:15

2 Kókó awọn ibukun naa rọ̀ mọ́ ireti bibọ̀ Messia, Gẹnẹsisi 49:1, 10-12, 18, 24

3 Jakọbu, ẹni iwa-bi-Ọlọrun, naa kú, Gẹnẹsisi 49:28-33

## ALAYE

Orukọ Jakọbu jẹ eyi ti kò ṣajeji si gbogbo awọn oluka Bibeli, o si jẹ eyi ti a maa n pe ni ọpọlọpọ igba mọ orukọ Ọlọrun, gẹgẹ bi a ti maa n sọ pe "Ọlọrun Jakọbu." O dabi ẹni pe kò si orukọ ẹlomiran ti a n pe mọ́ Ọlọrun nigbakuugba ju ti Jakọbu lọ. Nibi ti Jakọbu pe ni Bẹtẹli, ti itumọ rẹ jẹ Ile Ọlọrun, ni o ti mọ Ọlọrun. Lẹhin igba naa ni a sọ ọ di mimọ́ ni Penieli ni ọna ajo rẹ lọ si ilẹ rẹ lẹhin igba ti o ti gbe ni Harani fun ogun ọdun tabi ju bẹẹ lọ. Jakọbu bẹru o si fẹran Ọlọrun, Ọlọrun si fẹran oun paapaa; Ọlọrun sọ nipa rẹ pe o ni agbara pẹlu Ọlọrun ati pẹlu ẹniyan. Nisisiyii a ti de igbẹyin igbesi-aye rẹ, a o si maa gbọ́ awọn ọ̀rọ ikẹyin rẹ.

Awọn ọrọ̀ ikẹyin awọn ọrẹ́ tabi iyekan wa ti n kú lọ ṣe pataki fun wa lọpọlọpọ. Nigba ti awọn ti o ba ṣọwọn fun wa ba de bebe odo nì, a maa n feti silẹ pẹlẹpẹlẹ lati gbọ ọrọ idagbere wọn, eyi ti o maa n fi ọkan wa balẹ ti o si n tu wa ninu nigba ti wọn ba ti kọja lọ. Ṣugbọn awọn ọrọ ikẹyin awọn eniyan Ọlọrun bi Abrahamu, Jakọbu, Mose ati Jọṣua ṣe pataki lọpọlọpọ ju, ki i ṣe nitori awọn eniyan wọnyii jẹ olori pataki laaarin Israẹli nikan, ṣugbọn nitori nikẹyin igbesi-aye wọn Ọlọrun fun wọn ni ẹbun isọtẹlẹ ti o tayọ, iru eyi ti wọn ko ni titi di igba ti wọn n kọja lọ.

Jakọbu ṣaisan; pẹlu ibẹru pe aisan naa le yọri si iku, Josẹfu mu awọn ọmọ rẹ mejeeji o si lọ lẹsẹ kan naa si ibi akete baba rẹ. Inu Jakọbu dun lọpọlọpọ si Josẹfu, ẹni nipa iranlọwọ Ọlọrun ti o ti de ipo giga ninu ijọba ilẹ Egipti; nigba ti Jakọbu gbọ pe ọmọ oun n bọ̀, o gbiyanju, o si joko lori akete rẹ ki o ba le ki i ati awọn ọmọ rẹ daradara.

Ṣe akiyesi bi Jakọbu ṣe bẹrẹ ọrọ rẹ pẹlu Josẹfu. "Ọlọrun Olodumare farahàn mi ni Lusi ni ilẹ Kenaani, o si sure fun mi." Lusi ni orukọ akọ́kọ́ ti a n pe Bẹtẹli nibi ti Jakọbu ti ri igbala. Nibẹ ni o ti bẹrẹ itan rẹ nitori nihin ni igbesi-aye rẹ gan an ti bẹrẹ (2 Kọrinti 5:17). Ṣaaju akoko naa, o jẹ ẹlẹṣẹ, o kun fun ẹ̀tan ati ọpọlọpọ ẹ̀ṣẹ miiran. O n dawọ le ati ṣe ohun pupọ lọna ti ara rẹ, ṣaaju ki o to pade Ọlọrun ni Bẹtẹli. Ṣugbọn lẹhin iyipada rẹ̀, a ri i pe o n fẹ ki Ọlọrun mu ifẹ ti Rẹ̀ ṣẹ ki O si ṣe ohun gbogbo gẹgẹ bi ilana Rẹ̀. Yatọ si pe o ni igbala, Jakọbu kọ ẹkọ iyebiye ni Bẹtẹli. Lẹyin igbala yii o ti di ẹda titun, nitori naa, o tọka si akoko yii bi ibẹrẹ igbesi-aye rẹṣẹ.

Boya ọpọlọpọ eredi wà ti Josẹfu fi jẹ ọmọ ọwọ́n ninu awọn mejila. A mọ pe o jẹ ẹni ti o nironu, ti o si ni iwa rere, ati pe nigba ti o wà ni ọmọde, baba rẹ fun un ni ẹwu alarabara kan, ti ko kan fi bi baba rẹ ti fẹ ẹ ju awọn iyoku lọ hàn, ṣugbọn ti o le fun un ni àṣẹ pataki kan ti awọn iyoku kò ni. Lai si aniani Josẹfu fẹran Ọlọrun lati igba ewe rẹ wá, ati nitori ifaramọ timọtimọ pẹlu baba rẹ, o ṣe e ṣe ki o ti gbọ ninu itan nigba pupọ nipa awọn majẹmu ti Ọlọrun da pẹlu Abrahamu, Isaaki ati baba rẹ. O jẹ ọmọ ti Jakọbu ẹni ti o ni ibẹru Ọlọrun le fi ọkan tán ti o si le ba yin Ọlọrun logo.

Nisisiyii, ni opin igbesi-aye rẹ, Jakọbu fẹ fi ère fun ọmọ rẹ oloootọ ni ọna pataki kan. Dipo ti i ba fi sure fun Josẹfu gẹgẹ bi o ti ṣe fun awọn iyoku, o sure fun awọn ọmọ Josẹfu mejeeji, o si sọ wọn di ọmọ ara rẹ̀ pẹlu gbogbo anfaani ati ẹtọ ti awọn ọmọ oun funra rẹ ni. Wọn o jẹ baba awọn ẹ̀ya, eyi ti yoo fun Josẹfu ni ilọpo meji ninu ogún -- ọkan ninu ibukun ogún-ibi ti Reubẹni -- akọbi sọnu. Nigba kika eniyan kin-in-ni, ni aginju Sinai, ẹya Manasse ati Efraimu jẹ ọkẹ mẹta aabọ o le ẹẹdẹgbẹrinla (72,700) eniyan – lati ọmọ ogun ọdun soke – ti o le lọ si ogun. Eyi mu ki ipin Josẹfu jẹ ọkan ninu eyi ti o tobi ju ninu gbogbo ẹya Israẹli.

A ni apẹẹrẹ pupọ ninu Bibeli nibi ti Ọlọrun ti pa aṣà ati ilana eniyan tì sapa kan lati le fi ilana ati aṣẹ ti Rẹ̀ lelẹ̀ tabi lati la ọna ti Rẹ̀ silẹ fun ẹda ni ọna ti o yá ju (Orin Dafidi 115:3; 135:5, 6). Nigba miiran pẹlu Ọlọrun maa n pa ofin ogún-ibi tì sapa kan a si maa fi aburo ṣaaju ẹgbọn; Oun fi oju rere ati ibukun lati Ọrun wa fun ni gẹgẹ bi o ti tọ́ ninu ọgbọ́n ailopin Rẹ̀.

Ẹkọ iṣina kan ti o gba aye kan, eyi ti John Calvin kọ́ fi kọ ni, ti a si n pe ni ẹkọ Calvin, ti di apa kan ti awọn ẹlẹsin ti ki i ṣe Aguda (eyi nì ni awọn Protestants) gbagbọ. O kọ ni pe Ọlọrun ti yan awọn ti yoo ri igbala tẹlẹ, yoo si dari awọn iyoku si ọrun ègbé. Ninu ẹkọ iṣina yii ni ẹkọ igbala ayeraye fun gbogbo ẹni ti o ba ti gbagbọ wà, pe bi eniyan ba ti le di ẹbi Ọlọrun lẹẹkan ko tun le ṣe e ṣe ki a tun ya ẹni naa kuro ninu ibarẹ pẹlu Ọlọrun tabi ki o tun ṣegbe mọ.

Ẹkọ eke wọnyii duro le awọn ẹsẹ Bibeli ti wọn fa yọ lai ka awọn ẹsẹ iyoku si, ti wọn si n lọ wọn lọrun. Wọn gboju fo ipe Ihinrere si gbogbo ẹni ti o ba fẹ, ṣugbọn ẹkọ wọnyii jinna si otitọ Ọrọ Ọlọrun. A kò gbọjẹgẹ fun awọn eniyan yii a ko si fara mọ ẹkọ wọn. Ọrọ Ọlọrun kọ wa pe Ọlọrun ti pese igbala silẹ fun gbogbo eniyan nipa Jesu Kristi; ẹnikẹni ti o ba yàn ni o le ri igbala; ati pe o ṣe e ṣe lati sọ igbala naa nù bi eniyan ba mọọmọ yí pada kuro lọdọ Ọlọrun ti o si dẹṣẹ.

Lati yan awọn ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun kan kuro lara awọn ẹsẹ ti wọn ba lọ, ki a si bẹrẹ si lọ́ itumọ wọn lati fi idi ẹ̀kọ́ kan ti a ti gbin sinu ọkan wa mulẹ, lai gbe ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun wọnyii lori gbogbo otitọ Ọrọ Ọlọrun ti o wa ninu Bibeli, jẹ ohun ti o lodi si ilana ẹkọ Bibeli ati si ọkàn awọn oloootọ. Ṣugbọn ohun ti awọn ọmọ-lẹyin Calvin n ṣe ni eyi, a si mọ daju pe Ọlọrun lodi si iru igbekalẹ yii.

Ipe Ọlọrun si ironupiwada jẹ ti gbogbo eniyan. "Ẹni ti o ba fẹ" ti o wa ninu Bibeli to ẹri lati tẹ olukuluku eniyan lọrun pe ko si ẹni ti a tanu kuro ninu ipe nla lati dara pọ mọ ẹbi Ọlọrun. Lọna keji a ko le sọ pe ko si ohun ti a n pe ni ayanmọ́, tabi yiyàn; ṣugbọn nigba ti a ba ka Ọrọ Ọlọrun a o ri i pe ayanmọ kò si ninu ipe Ọlọrun si ironupiwada, ṣugbọn o wà fun awọn ipo oye kan tabi awọn ipe pataki kan ninu iṣẹ Ọlọrun laye.

Bi Ọlọrun ti n yan awọn eniyan kọọkan lọkunrin ati lobinrin fun ipo oye pataki ninu ọgba ajara Rẹ̀ ati ninu Ijọba Rẹ̀ jẹ́ eyi ti Ọlọrun n ṣe ninu ọgbọ́n awamaridi Rẹ̀ ati imọtẹlẹ ero, ilana, ete ati ipinnu olukuluku eniyan, lọkunrin, lobinrin ati lọmọde – i baa jẹ pe o ti ni igbala tabi ko i ti ni. Ọlọrun mọ awọn ọmọ-eniyan ti yoo fẹran Oun, ti yoo si sin Oun pẹlu gbogbo ọkan wọn. O mọ̀ awọn ti yoo fi tifẹtifẹ ṣe irubọ nla ati iyara-ẹni sọtọ kikun nitori iṣẹ Oun. O mọ̀ awọn ẹni ti yoo ka ẹ̀gan Agbelebu si ọrọ̀ ti o ga ju gbogbo alumọni aye yii lọ. Awọn ẹni

iwa-bi-Ọlọrun wọnyii, awọn eniyan mimọ́ ati awọn ti n fi ara wọn rubọ wọnyii ni Ọlọrun n pe fun iṣẹ pataki ati anfaani ninu Ijọba Rẹ̀ (1 Peteru 1:1, 2;  2:9, 10;  Efesu 1:4-12).  Bi ayanmọ́ ti mọ ni eyi.  Ko kan idahun wa si ipe Rẹ̀ si "olukuluku ẹniti ongbẹ ngbẹ" tabi idahun Ọrun si "Oluwa ṣaanu fun mi" ti "ẹni ti-o-ba-fẹ."

Yiyan ti Ọlọrun n yan ẹni kọọkan lati inu ogunlọgọ awọn eniyan ti o n rin ipa ọna ayé yii bi a ti ri i duro le ohun meji.  Ekinni, nipa iha ti a kọ bi ẹni kọọkan si ipe Rẹ̀ si ironupiwada ati rírọ̀ ti Oun tun n rọ̀ wa lẹyin naa lati sun mọ Oun timọtimọ.  Ekeji duro le imọtẹlẹ Ọlọrun nipa ọna ti a o fi jẹ ipe Rẹ̀ ati iha ti a o kọ si rírọ̀ ti Oun yoo rọ̀ wa.

Ọlọrun yan Abẹli dipo Kaini – nitori Ọlọrun mọ pe nipa igbagbọ Abẹli yoo ru "ẹbọ ti o san ju ti Kaini lọ." Ọlọrun yan Isaaki dipo Iṣmaẹli – nitori Isaaki jẹ ọmọ ileri ati pe Olodumare mọ pe ọmọ ileri yii yoo jẹ ẹni ti yoo bẹru Ọlọrun ti yoo si bọla fun Un ni gbogbo ọjọ aye rẹ̀.  Ọlọrun yan Jakọbu dipo Esau – **nitori** ki a to bi awọn ibeji yii Ọlọrun mọ pe Jakọbu yoo ka ogún ibi ati ibukun Ọrun si ju ohunkohun ti o wa ninu aye lọ ati pe Esau yoo kẹgan, yoo si ta ibukun ati anfaani iyebiye wọnyii fun "ipẹtẹ" lasan.

Ọlọrun yan Judah ati Josẹfu dipo Reubẹni – nitori Ọlọrun, ti oju Rẹ̀ ri ohun gbogbo, ri i pe awọn mejeeji yoo gbe igbesi aye ẹni iwa-bi-Ọlọrun ju arakunrin wọn ti ọkan rẹ kun fun ifẹkufẹ.  Ọlọrun yan Mose ni aṣaaju fun Israẹli dipo ẹgbọn rẹ agba, Aarọni, nitori ipinnu kan wa ni ọkan rẹ ti yoo yàn "lati mã ba awọn enia Ọlọrun jiya." Ọlọrun yan Dafidi ni ọba fun Israẹli dipo eyikeyi ninu awọn arakunrin rẹ nitori ọkan ọmọ kekere oluṣọ-agutan ni pe niwaju Ọlọrun -- Ọlọrun si mọ bẹẹ lati ibẹrẹ!

Nipa bayii a le mọ pe imọtẹlẹ Ọlọrun ati ọgbọ́n awamaridi Olodumare le ri opin lati ibẹrẹ, ki O si mọ ero ọkan wa ju bi awa paapaa ti mọ lọ.  A ko le diwọn oye Rẹ̀, bi kò ba ṣe bẹẹ ni, Oun ki ba ti jẹ Alagbara lori ohun gbogbo, Ẹni ti o mọ ohun gbogbo ati Ẹni ti O wa ni ibi gbogbo gẹgẹ bi a ti mọ Ọn si.  Bi o ba ṣe pe iwa mimọ Rẹ̀, ifẹ, aanu ati idajọ Rẹ̀ ko niwọ̀n, ko si ni opin tabi ipari, nigba naa, imọtẹlẹ Rẹ̀ jẹ eyi ti ko ni aalà bakan naa (Isaiah 42:9;  46:9, 10;  Iṣe Awọn Apọsteli 15:18).  Oun le mọ, O si mọ dajudaju  igbesi-aye wa ni kinnikinni ani titi de opin aye wa.

Ṣugbọn imọtẹlẹ Baba ayeraye yii ko gba agbara lati yan kuro lọwọ wa -- ifẹ nla ati giga lati le yan fun ara wa ti Ọlọrun fi fun wa lati atetekọṣe.  O wa lọwọ olukuluku lati yan ibugbe ayeraye.  Ẹbi ko si fun ẹnikẹni bi a ba fi ọwọ ara wa yan ọna gboorò ti a si ṣegbe.  Agbara lati dayan wà ti a fi fun wa ti Ọlọrun paapaa kò le ṣakoso rẹ tabi yi pada, ti a ba saa ti le ṣe ipinnu.

Nitori naa, "awọn ti o ti mọ tẹlẹ" ni o si ti yan tẹlẹ lati ri bi aworan Ọmọ Rẹ̀, Jesu Kristi.  Awọn ti O si ti yan tẹlẹ ni O n pe si oriṣiriṣi ipo oye ninu isin Rẹ̀.  O wa lọwọ olukuluku lati yan, ṣugbọn Ọlọrun mọ ohun ti olukuluku yoo yan, yoo si pe e fun iṣẹ isin pataki lọna bayii pe "Niwọn bi ẹni yii yoo ti yan lati tẹle mi, Emi yoo pe e fun ipo yii ninu Ijọba mi ati ninu iṣẹ mi ni aye."  Awọn ni ẹni ti Ọlọrun dalare, nigba ti wọn kigbe pe E ni ironupiwada, awọn si ni ẹni ti yoo ṣe logo (Ka Orin Dafidi 4:3; ati Romu 8:28-31).

Ọlọrun ri i pe Josẹfu yoo jẹ ẹni ti Oun le gbẹkẹle, nitori naa O pe ọmọdekunrin yii si aye pataki ninu eto Ọlọrun fun igbala araye.  Nisisiyii, Ọlọrun ti O n ti ẹnu iranṣẹ Rẹ̀ Jakọbu sọrọ, pa ofin ẹda ti sapa kan lati yan Efraimu ni aṣaaju dipo Manasse ti i ṣe ẹgbọn.  Titobi ni ọna Ọga-ogo!  Eto Rẹ̀ ti ga to, o si ti jinlẹ to!  O si ti ni iyin to laaarin awọn ọmọ eniyan, Ẹni ti O da aye yii ti O si n boju to ohun gbogbo ti o n ṣẹlẹ ninu rẹ finnifinni! Bawo ni i ba ti dara to fun wa lati rẹ ara wa silẹ buruburu bi a ti n sun mọ Itẹ Rẹ̀ ati bi a ti n rin niwaju Rẹ̀ ninu aye yii.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni orukọ awọn ọmọ Josẹfu mejeeji.

2 Darukọ awọn ọmọ Jakọbu mejeejila.

3 Ibukun pataki wo ni a fun Josẹfu?

4 Ta ni a fi ipin ọba ninu ogun-ibi Reubẹni fun?  Ki ni o wà ninu rẹ̀?

5 Bawo ni a ṣe mu asọtẹlẹ nipa Lefi ṣẹ?

6 Fi Bibeli gbe asọtẹlẹ nipa Messia ti o wa ninu ire ti Jakọbu su fun awọn ọmọ rẹ lẹsẹ.

7 Ki ni aṣa eniyan ti Ọlọrun pa ti si apa kan nigba ti Jakọbu sure fun awọn ọmọ Josẹfu?

8 Ṣe alaye nipa awọn ọna ti Ọlọrun ti fi yàn wa tẹlẹ.

9 Ki ni Jakọbu tọka si nigba ti o bẹrẹ ọrọ rẹ pẹlu Josẹfu?

10 Nibo ni a sin Jakọbu si?